# IKẸYIN ỌJỌ́

# 1 Timoteu 4:1-9; 2 Timoteu 3:1-7

# ẸKỌ 414 --- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Ṣugbọn eyi ni ki o mọ̀, pe ni ikẹhin ọjọ igbà ewu yio de" (2 Timoteu 3:1).**

**Yoo Tun Pada Wá**

Jesu kọ́ awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ pe Oun yoo tun pada wá si ayé. O ni "Emi nlọ ipèse àye silẹ fun nyin. Bi mo bá si lọ ipèse àye silẹ fun nyin, emi o tún pada wá, emi o si mu nyin lọ sọdọ emi tikarami; pe nibiti emi gbé wà, ki ẹnyin le wà nibẹ pẹlu" (Johannu 14:2, 3). Ileri miiran tun wà nipa bibọ̀ Jesu ti a kọ silẹ ninu Iwe Iṣe Awọn Apọsteli. Gẹgẹ bi Jesu ti n bá awọn eniyan naa sọrọ, "bi nwọn ti nwò, a gbé e soke; awọsanma si gbà a kuro li oju nwọn" (Iṣe Awọn Apọsteli 1:9). Jesu goke lọ si Ọrun ṣugbọn bi awọn eniyan naa ti n wò O bi a ti n gbà a lọ kuro ni oju wọn, awọn ọkunrin meji ninu aṣọ funfun wá wọn si wi pe, "Jesu na yi, ti a gbà soke ọrun kuro lọwọ nyin, yio pada bẽ gẹgẹ bi ẹ ti ri i ti o nlọ si ọrun" (Iṣe Awọn Apọsteli 1:11).

Ileri bibọ̀ Jesu yii ni o ti jẹ́ ireti gbogbo awọn Onigbagbọ́. Ireti yii a maa mu ki wọn maa ṣọna ki wọn si maa gbadura. Ireti bibọ̀ Jesu a maa fun wọn ni okun lati murasilẹ fun ọjọ naa ti Jesu yoo dé lati wá mú Iyawo Rẹ̀ ti n duro de E lọ.

**Igba Ikẹyin**

Ni ibi pupọ ninu Bibeli ni a ti darukọ "igba ikẹhin" itumọ eyi ti i ṣe awọn ọjọ ti yoo ṣiwaju bibọ Jesu. Nigba kan awọn ọmọ-ẹyin beere lọwọ Jesu, "Kini yio si ṣe àmi wiwa rẹ, ati ti opin aiye?" (Matteu 24:3). Jesu sọ ọpọlọpọ nnkan ti yoo ṣẹlẹ fun wọn: ọpọlọpọ eniyan ni awọn wolii èke yoo tanjẹ; ifẹ́ ẹ̀ṣẹ yoo pọ̀ si i; a oo korira awọn Onigbagbọ́ nitori orukọ Jesu; ọpọlọpọ yoo sọ ifẹ Ọlọrun nù kuro ninu ọkàn wọn. Jesu sọ awọn àmi miiran nipa bibọ Rẹ̀ ṣugbọn O wi pẹlu pe, "Ṣugbọn ẹniti o ba fori ti i titi de opin, on na li a o gbalà" (Matteu 24:13).

**Igbà Ewu**

Abájọ ti Paulu fi kọwe si Timoteu pe ni igba ikẹyin igba ewu yoo dé. O sọ siwaju si i pe igba ikẹyin yoo kún fun ewu ati fifi ẹmi wewu. Timoteu jẹ́ ọdọmọde alufaa Paulu si n fẹ ran oun ati awọn Onigbagbọ́ miiran lọwọ pẹlu. Awọn eniyan a maa wi pe – ogun agbọtẹlẹ ki i pa arọ -- bi a ba fun eniyan ni anfani lati mọ̀ tẹlẹ nipa nnkan a ti funni ni anfaani lati murasilẹ. Paulu ko sọ pe oun ni òye diẹ pe awọn nnkan kan yoo ṣẹlẹ ni igba ikẹyin, bẹẹni kò si wi pe oun rò pe awọn nnkan wọnyii yoo ṣẹlẹ. Paulu sọ jade gbangba pe "Ẹmi ntẹnumọ ọ" bi yoo ti rí ni igba ikẹyn yii. Ki ni Ẹmi? Bibeli wi pe, "Ẹmi li o si njẹri, nitoripe otitọ li Ẹmi" (1 Johannu 5:7).

**Ẹtan**

Ẹmi ni o misi Paulu lati ṣe ikilọ pe Satani yoo wá pẹlu ọrọ ẹtan -- ọrọ lati dán eniyan wò ati lati tan ni jẹ. O dara lati mọ Ọrọ Ọlọrun ki a ma ba ti ẹni naa lọ sinu aṣiṣe. Nigba ti eniyan bá n gbé igbesi-ayé iwa-bi-Ọlọrun, ko yẹ ki o tun bẹru pe a le ṣi oun lọna. "Iwa-bi-Ọlọrun li ere fun ohun gbogbo, o ni ileri ti aiye isisiyi ati ti eyiti mbọ̀." Awọn Onigbagbọ ni lati fi iwa-bi-Ọlọrun ṣe iwà hù -- nigba naa wọn oo ni aabo kuro lọwọ ẹtan Satani. Ọpọlọpọ igba ni Satani maa n dan eniyan wò nipa sisọ pe ki i ṣe ọranyan lati gbé igbesi-ayé ti o dara to bayii; pe ki i ṣe dandan lati mú ohun ti o wọ́ bọ̀ si titiọ; pe ki i ṣe ọranyan lati ka Bibeli lojoojumọ ati lati gbadura pupọ. Ọta nì mọ̀ pe agbára Onigbagbọ́ a maa ti ọdọ Ọlọrun wá nipa Ọrọ Ọlọrun ati adura igbagbọ́.

Ni igba ayé awọn Ọmọ Israẹli, ọba wọn, Jeroboamu, wi pe, "O pọ̀ju fun nyin lati mã goke lọ si Jerusalẹmu" (1 Awọn Ọba 12:28) lati lọ jọsin. Dipo ti wọn i bá fi maa jọsin nibi ti Ọlọrun wi fun wọn, ọba naa ṣe ibi titun ati àse titun "ti o rò li ọkàn ara rẹ̀" "gẹgẹ bi àse" ti Ọlọrun beere. Ẹṣẹ ni eyi, Ọlọrun si rán idajọ si ọba naa: ọwọ rẹ̀ si "gbẹ, bẹ̃ni kò si le fa a pada sọdọ rẹ̀ mọ." O si tun rán idajọ si pẹpẹ naa: o si "ya, ẽru na si danù kuro ninu pẹpẹ na" (1 Awọn Ọba 13:4, 5).

O tọ́ ki awọn Ọmọ Israẹli gbọ́ ti Ọlọrun ju ti ọba lọ. Fi ọ̀rọ awọn eniyan wé ọ̀rọ Bibeli, bi ọ̀rọ awọn eniyan kò ba ti kọ́ni ni ẹ̀kọ́ ti o bá ti Bibeli mu, ṣọra ki a ma ba mu ọ ṣina kuro lọdọ Ọlọrun. Ọna kan wà ti o dabi ẹnipe o dara ni oju eniyan ṣugbọn opin rẹ̀ ikú ni (Owe 14:12; 16:25).

**Ẹlẹsin**

A kilọ fun wa lati yẹra kuro lọdọ awọn ti wọ́n ni "afarawe iwa-bi-Ọlọrun, ṣugbọn ti nwọn sẹ́ agbara rẹ̀." Ọpọlọpọ ni o wà ti wọn ni ẹsin ṣugbọn ti wọn ko ni Jesu ninu ọkàn wọn, nitori naa wọn kò le gbé igbesi-ayé bi ti Jesu. A kà ninu Johannu 1:12: "Ṣugbọn iye awọn ti o gbà a, awọn li o fi agbara fun lati di ọmọ Ọlọrun, ani awọn na ti o gbà orukọ rẹ̀ gbọ́." Oluwa a maa fun eniyan ni agbára lati wà fun Un ati lati gbé laisi ẹ̀ṣẹ. Ninu Johannu 8:34 a kà pe, "Ẹnikẹni ti o ba ndẹṣẹ, on li ẹrú ẹ̀ṣẹ." Ẹni ti o bá n dẹṣẹ ki i ṣe ọmọ Ọlọrun ṣugbọn ti eṣu ni, nitori pe "ẹnikẹni ti a ti ipa Ọlọrun bí, ki idẹṣẹ" (1 Johannu 3:8, 9).

**Apẹyindà**

Ni igba ikẹyin "awọn miran yio kuro ninu igbagbọ́" -- awọn miiran ninu awọn ti wọn ti fẹ Oluwa ti wọn si n tẹle E ki yoo tun ṣe bẹẹ mọ́. Jesu wi pe, "Nitori ẹ̀ṣẹ yio di pipọ, ifẹ ọpọlọpọ yio di tutù" (Matteu 24:12). Ẹṣẹ kanṣoṣo yoo ya eniyan nipa kuro lọdọ Ọlọrun, bi ẹni naa kò bá si jẹwọ ẹ̀ṣẹ yii ki Ọlọrun si dariji i, ẹni naa yoo jẹ́ apẹyindà lọdọ Ọlọrun. Satani a maa sọ fun iru eniyan bẹẹ pe ki o maa bá ọ̀na rẹ̀ lọ bẹẹ, pe kò si ẹni ti yio mọ̀, ati pe awọn eniyan yoo fi rẹrin ẹlẹya bi o ba jẹwọ pe oun ti ṣe ohun ti kò tọ́. Igbá ikẹyin jẹ́ akoko ewu. Eniyan ni lati fetisi ohùn Ọlọrun ki o si di eti rẹ̀ si ohùn Satani.

**Ẹri Ọkàn**

Ẹni ti o ba ti "kuro ninu igbagbọ́" ni àyè lati yan ọ̀kan ninu nnkan meji. O le ronupiwada, ki o kọ ọ̀na rẹ̀ silẹ, ki o si yipada si Ọlọrun ẹni ti yio ṣaanu fun un ti yoo si "fi ji li ọpọlọpọ" (Isaiah 55:7). Gẹgẹ bi ẹlẹṣẹ miiran, o le wá si ọdọ Ọlọrun. Nigba ti o dẹ́ṣẹ̀ a mú ododo rẹ̀ kuro bẹẹni ikú ayeraye si n rọ̀ dẹ̀dẹ̀ lori rẹ̀ (Esekiẹli 18:24). Ninu Esẹkiẹli 18:20 a kà pe "ọkàn ti o ba ṣẹ̀, on o kú," ṣugbọn a kà a siwaju si i a si ri i pe Ọlọrun kò ni inudidun pe ki eniyan buburu ki o kú ṣugbọn O fẹ ki o "yipada kuro ninu ọ̀na rẹ̀, ki o si yè" (Esekiẹli 18:23).

Yiyàn keji ni lati wà ninu ẹ̀ṣẹ sibẹ, jinna si Ọlorun, laisi ireti tabi alaafia. Ẹri ọkàn rẹ̀ yoo wá séle si ohùn Ẹmi tabi ki o dabi eyi ti a fi irin gbigbona jó. O mọ̀ bi ẹri ọkàn rẹ ti maa n sọ fụn ọ pe ki o gbadura, bi o ba si kọ̀ lati tẹti lelẹ iwọ yoo maa lọ bẹẹ titi ẹri ọkàn rẹ ki yoo tún wahala rẹ mọ́ nitori aigbọran rẹ iwọ yoo si gbagbe lati gbadura -- iwọ yoo di alailagbara iwọ yoo si ṣubu sinu idanwo. Eniyan ni lati ṣọra ki ẹri ọkàn rẹ̀ má ba séle – ti ki yoo tun le kaanu fun iwa aitọ́ ti o n hù, ti ki yoo tun rọrun fun u nigba ti Ọlọrun bá n bá a sọ̀rọ̀ nipa aigbọran rẹ̀ ti ki yoo si tun bikita mọ́ nigba ti igbesi-ayé rẹ̀ kò tẹ́ Ọlọrun lọrun.

**Ami**

Awa mọ̀ pe igba ikẹyin ni a wà yii. Paulu ṣe alaye irú igbesi-ayé ti ọpọlọpọ yoo maa gbé ni igba ikẹyin. Wọn o kún fun imọ-ti-ara-ẹni-nikan; bẹẹ ni igbesi-ayé ọpọlọpọ eniyan si ri lode oni. Wọn o jẹ́ afunnu; eyi si ni nnkan ti a n rí lonii. Wọn o jẹ́ onikupani, bẹẹni lode oni o ṣoro lati gbẹkẹle awọn miiran, bi a tilẹ kọ ileri ti wọn ṣe silẹ. Wọn o jẹ́ alailọpẹ; a si ri i pe lode oni, diẹ ni awọn eniyan ti o n dupẹ lọdọ Ọlọrun tabi ẹnikẹni fun ibukun ati ojurere. Wọn o jẹ́ olufẹ faji ju olufẹ Ọlọrun lọ; bẹẹni awọn eniyan n lepa faaji nigbagbogbo dipo ti wọn i bá fi wá Ọlọrun. Wọn o maa fi "igbagbogbo kẹ́kọ, nwọn kò si le de oju imọ otitọ." Iwe ati ile-ẹ̀kọ́ pọ̀ lode oni ju igba atẹyinwá lọ, awọn eniyan ni anfaani lati kẹ́kọọ ṣugbọn o dabi ẹnipe bi awọn miiran ti n pọ̀ si i ninu imọ iwe to bẹẹ gẹgẹ ni wọn n lọ jinna kuro ninu ìmọ Ọlọrun tó.

**Opin Igba**

Jesu fi àmi ti o loye funni niti igba ikẹyin, gbogbo awọn wọnyii ni o si ti ṣẹlẹ̀. O ni: "Ẹnyin o si gburo ogun ati idagiri ogun … ṣugbọn opin ki iṣe isisiyi" (Matteu 24:6). O ni: "Iyan, ati ajakalẹ-arùn, ati isẹlẹ, … Gbogbo nkan wọnyi ni ipilẹṣẹ ipọnju" (Matteu 24:7, 8). Jesu wi pe: "A o si wasu ihinrere ijọba yi ni gbogbo aiye lati ṣe ẹri fun gbogbo orilẹ-ède; nigbana li opin yio si de" (Matteu 24:14). Olukuluku orilẹ-ède ni awọn Onigbagbọ́ ajihinrere ti tọ lọ lati kede Ihinrere fun wọn – Tibet si ni orilẹ-ède ti o kẹyin lati gba awọn ajihinrere làye lati wọ ilẹ wọn. Ọpọlọpọ asọtẹlẹ nipa awọn Ju ni o si ti ṣẹ pẹlu. "Nigbana li opin yio si de." Igba ikẹyin le jẹ igba ti o kún fun ẹ̀ru fun awọn ẹlomiran ṣugbọn o le jẹ́ ọjọ iyanu fun Onigbagbọ́ nitori o mọ̀ pe Jesu fẹ́rẹ dé. Ọjọ diẹ si i ni o kù lati rìn nipa igbagbọ́! Ọjọ diẹ si i ni o kù lati fi ṣiṣẹ fun Un! Ọjọ diẹ si i ni o kù lati murasilẹ fun bibọ̀ Rẹ̀ ati lati jère ìti diẹ si i lati mú wá si ẹsẹ̀ Rẹ̀! Ọjọ ẹ̀ru nla tabi ọjọ ologo? Iwọ ha nwo ọ̀na fun bibọ̀

Jesu? Ninu Heberu 9:28 a kà pe: “Yio farahan nigbakeji laisi ẹ̀ṣẹ fun awọn ti nwo ọ̀na rẹ̀ fun igbala.”

**AWỌN IBEERE**

1 Ta ni kọ Timoteu 1 ati 2?
2 Ta ni Timoteu i ṣe?
3 Ki ni itumọ “igba ikẹyin”?
4 Sọ diẹ ninu Iwe Mimọ́ ti o n sọ nipa bibọ̀ Jesu lẹẹkeji?
5 Sọ oriṣiriṣi awọn àmi igba ikẹyin?
6 Ki ni Jesu wi nipa igba ikẹyin?
7 Ki ni itumọ pe ki eniyan “kuro ninu igbagbọ́”?
8 Bawo ni ẹri-ọkàn eniyan ṣe séle?
9 Bawo ni eniyan ṣe le mọ̀ pe ọmọ Ọlọrun ni oun i ṣe?
10 Pari gbolohun yii: “Ṣugbọn ẹniti o ba foriti i titi de opin … ” (Matteu 24:13).